# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO ŞE WI LEJO'

VOL XIV NO 904 LAGOS SATURDAY JAN. 18 — JANUARY 24 1964 KOBO MEJI


KINNI ELEYI O.... ?

# Ijoba Fe Ko Ara Olowogbowo Lo Si Okun Alasia Nitori Kereni Tuntun

**EKO — Ọrẹ bẹhin yọ ni owurọ ana nigbati a gbọ irohin a gbọ irohin a gbọ yanu kan nipa awọn enia kan ni adugbo kan ni Olowogbowo l'Eko ti Ijọba Apapọṣe fẹ ko kuro ninu ile wọn lọ si OKUN ALASIA nitori Kereni tuntun ti nwọn fẹ kọ şekeji eyi ti a nlo lọwọ nisisiyi Gẹgẹbi irohin ti a gbọ a to ẹdẹgbarin enia ti nwọn ni lati ko ile fun ninu ilẹ titun ti nwọn fẹ gba ni Okun Alaşia na.**

Onirohin wa ni nigbati on toju bọ iwe kan nibi iṣẹ awọn fọle fọle, on ri wipe adugbo mẹta pataki ni awọn alaşẹ fọlefọle na ni lati gba patapata lọwọ awọn onile Awọn adugbo na ni Apongbọn, Ẹlẹgbata ati Alakoro. Gbogbo ilẹ ti Ijọba a fẹ lo na a to iwọn eeka mejila (12 acres), awọn akọwe wonlewonlẹ si ti wọn wọn lọjọ ti o pẹ.

A gbọ wipe lọna Ijọra ni nwọn yo gbe ọna kereni tuntun na gba kişe Ebute-Metta, ni orina ni nwọn şe fun awọn Aganyin apeja ti o ngbe Okun Alasia ni iwe-pajawiri miran ni ijẹta wipe ki nwọn tete ko awọn ẹru wọn kuro nibẹ nitoripe awọn fẹ wo gbogbo awọn ile ti nwọn kọ sibẹ awọn fẹ lo ibẹ ni kiakia.

Ni ọsan ana gbogbo awọn enia ti nwọn ngbe Okun Alasia ni Apesẹ ati Oko Kuku ni nwọn npalemọ ẹru wọn ni kiakia nigbati awọ a'ọwe Ilewiwo (L.E DB) wa sọ fun wọn wipe ni ọtunla Ọjọ Aje ni awọn yio ma wo le wọn.

## Dokita Okpara Gba Awon Omo Egbe Alakuko Ibadan Ni Bolu

BENIN CITY:— Orişirişi ọtẹ 'ati tẹmbẹlẹkun ni o mbẹ silẹ larin awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ni Ipinlẹ Iwọ Oran lati nkan bi oşu mọkanla wa, ọkan ninu tẹmbẹlẹkun kan ti awọn ọga-ẹgbẹ na tun fọ ju silẹ ni Benin ni irọlẹ ana ni tituka ti nwọn tu awọn igbimọ ẹgbẹ na ka ni Ibadan ti nwọn gba agbara lọwọ wọn, ti nwọn si yan awọn oloye mẹrin kan dipo wọn,

Orukọ Awọn ti a gbọ wipe nwọn yan ni igbimọ afunn'sọ dipo awọn oloye ọmọ ẹgbẹ Alakuko (N C N C) ti nwon nja lori ọrọ oye na ni Dokita K. O. Mbadine (alaga) Ẹgbẹni R. B. K. Okafor, minisita kekere l'Eko Loya A. Ogunsanya at Kẹhinde Sofọla.

A gbọ wipe ọrọ na ko ṣa [illegible] ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NC[illegible]C) Ibadan lọrun rara, Nwọn ni b[illegible] o ba ti gba niwọn yio fun un [illegible] awọn ko [illegible] kinwọn ma fi awọn Ibo şe ọga awọn ni ipinlẹ Yoruba.

Irohin ti a tun gbọ lati Ibadan losan ana ni wipe awọn ogunna gbon bo ẹgbẹ na ti nko ara wọn jọ lati şe ipade nla ka l'Oke Mapp ni Ibadan ni irọlẹ ọla.

Ogbẹni [illegible] O Akinjide tişe ikilọ fun awọn oloye Ap.pandodo ti Dokita Okpara yan fun wọn wipe awọn ko gbọdọ rẹsẹ enikan ni Ibadan ninu wọn ti nwọn ko ba fẹ ijangbọn.

Ija Awolowo Ati Akintola Fe Pari ?

## Oba Oni Ni Oduduwa Ni Nje Olofin

IBADAN — Awọn Yoruba ni agbalagba ki wa lọja ki ori omọtuntun wọ, Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi, Ọni Ile Ifẹ ti dide si ija ti o wa larin awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (A G) pẹlu Oloye S L Akintọla, olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Oran, lati nkan bi ọdun meji lati pari rẹ fun wọn.

A gbọ wipe Ọba Ọni pe Alhaji D. S, Adegbenro tişe adele olori awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ( AG ) sinu ile rẹ lati ba a sọrọ kẹlẹkẹlẹ kan ni owurọ ana, a ko mọ ọrọ ti Alaiyeluwa ba Alhaji Adegbenro sọ, şugbọn awọn sọrọsọrọ ti nwọn wa ni agbala ọba ni awọn ro wipe nipa bi ija na yio tişe pari ni nwọn jọ sọ.

(Wo yoku loju ewe [illegible])

# Awon Egbe Omo Yoruba Se Ipade L'Eko

EKO- Ni ijęlo ọjọ Abamẹta ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ tuntun kan ti nwon şęşę da silę l'Eko ti nwọn npe orukọ rẹ ni ẸGBẸ ỌMỌ YORUBA se ipade gbogbogbo kan ninu ile a p e j ọ glover ni Ehingbęti lori nkan ti awọn ọmọ ẹgbe na ba bọ i p a d e nla kan ti awọn b a awọn ọmọ ẸGBẸ Ọ M Ọ ODUDUWA pẹlu awọn ọba şe laipẹyi ni Ibadan.

O l o y e (Dokita) F. A, Akerele ni o şe a l a g a ipade na, D kita n a fi ọ r ọ orin titun ti olorin kan, Ọgbẹni Hurbert Ogunde, kọ laipẹ yi ti o n i ki awọn "YORUBA RONU" pa iwada şe akajuwa orisirisi iya ti o njẹ awọn ọmọ Yoruba jake jado nibi işẹ pataki-pataki.

Lẹhinti o ti sọrọ tirẹ tan ni nwọn pe Ọgbẹni S. A Lana, minista kekere ninu ilẹ işe alakoso Ijọba ilẹ Nigeria, ti o si jẹ ọkan ninu awọn oguna-gbongbo Ẹgbẹ oşelu, ẹgbẹ Olomi (NPC) ti iha ipinlẹ Iwo orun pe ki o sọ idi rẹ ti awọn şe pejọ fun ipade na.

Ọgbẹni Lana darukọ awọn orişirişi arun ti o mba awọn Ọmọ Yoruba ja yatọ si awọn ọmọ orilẹ ede miran O ni awọn Ọba ati awọn ijoye ilẹ Yoruba fi orukọ ẸGBẸ ỌMỌ ỌLỌFIN da ẹgbẹ awọn Ẹgbẹ ọmọ Yoruba pọ mọ ti awọn Ẹgbẹ ọmọ Oduduwa nisisiyi.

O tun şe alaye, o ni ni gbogbo ibi ile işẹ pataki pataki ni nwọn ti sọ awọn ọmọ Yoruba di ẹni ẹhin nisisiyi, o ni iya ti nwọn fi njẹ awọn ọmọ Yoruba pọ pupọju.

Oloye Fagbenro Beyioku ti o tun sọrọ ni ọna ti awọn alamọjuto I j ọ b a apapọşe ngba pin ọna işẹ meremere nişisiyi ko boju mu rara, o ni nwọn nfowọ rọ awọn ọmọ Yoruba sẹhin pupọ, gbogbo ibi ipo işẹ nlanla ti o yẹ ki nwọn to wọn mọ ni nwọn ko fun wọn.

Oloye Beyioku ni awọn ko da ẹgbẹ ọmọ Ọlofin silẹ lati ba nkan jẹ fun awọn Yoruba şugbọn lati tun nkan şe ni bi bẹkọ ni awọn adajọ adajọ, awọn lọba lọba ati ijoye ilu Yoruba ko ni lọwọ si i.

Awọn enia diẹ ti aye wa lati daruko ninu awọn ti nwọn wa si ibi ipade ẹgbẹ ọmọ Yoruba na ni Oloye P A Afolabi, ọkan ninu awọn agbalagba ọmọ ẹgbẹ Alakoko, Oloye Kọla Balogun, Adajọ S A Agbabiaka ati Lọya H, O. Davies

## Nwon Sinku Sadatu NiItori

ITORI:— Gbogbo ęsę awọn ọmọloku ati ẹbi wọn lo pọ si ibi isinku Ologbo Iya-afin Sadatu Adebiyi ti o jalaisi laipẹ yi ni Itori nibi. Ẹni ọgọta ọdun o i iya na, osi fi awọn mẹta saiye, ninu awọn ọmọ rẹ na ri Ọloye A S Adebiyi, Tiamiyu Adebiyi ati Asiata Adebiyi.

A ki awọn ọmọloku pẹlu awọn ẹbi ayo, awọn ku asẹhinde,

# Oba Adele Fi Alhaji Ojikutu Je Olotu

EKO:— Laipẹ yi ni a gbọ wipe Ọba Adeniji Adele fi Alhaji Azeez Ojikutu ti o ngbe Opopo Idoluwo l'Eko jẹ Oye Olotu fun 'wahala rẹ lori awọn enia ilu.

Ni Iga Idunganran ni Isalẹ Eko ni nwọn ti fi ewe oye le e lori. On si ni ẹnikinni ti nwọn kọ fi jẹ ioye tuntun ni i.

Ẹni ọdun mẹrinleladọta ni Alhaji Ojikutu o si jẹ ọkan ninu awọn alapata ẹran l'Eko. Oye a mọri o.

**Ka Irohin awon Omo Egbe Omo Oduduwa t'Eko ti nwon faake kori lori oruko OMO OLOFIN ni oju ewe Keta.**




Òkùnrin kò gbọdọ ṣummọ ẹani ati ẹbí mi. A nmu Ovaltine lojojumọ lati ni alekún ilera.
Wíré gyin, kòkó ati 'vitamins' ilera miran to wà ninu Ovaltine a mã fun wa ni ohun ilera to jẹ kòṣemáni fun ara.




fun ilera
agbara ati okun
*mu*
**OVALTINE**
*lojojumọ*

# Awon Omo Egbe Oduduwa Eko F'ake Kori Lori Oruko

EKO—Irohin ko to afojuba ni ipade nla k a n ti awon ỌMỌ ẸGBẸ ODUDUWA ẹka t'Eko ṣe ni irọ ẹ ọjọ Aie tiṣe ọjọ kẹtala oṣu kini ọdun yi ninu ile iwe awọn Ahmadiya ni Ẹlẹgbata; ki akoko ti nwọn fi ipade na si to to ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti pe s ba-siba silẹ bi o tilẹ jẹ wipe ọpọlọpọ awọn ogunna-gbo ngbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn lọ sibi isinku ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na Alhaji Issa Williams ti nwọn ngbe lọ si itẹ lọjọ na.

Ọmọba K L A Ọjọra ni nwọn yan ni alaga ipade ọjọ na, awọn enia pataki pataki ni nwọn sise isan-gbe rẹ, ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na lokunrin ati lobinrin ti nwọn wa ni Suru Lere, Mushin, Yaba Oju-owoye E b u t e Metta ati Abule Ijẹsha n i nwọn wa.

Ki nwọn to bẹrẹsi ọ r ọ sọ iranti awọn meta ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na ti Eko ti nwọn jalaisi ni nwọn kọ ṣe, awọn na ni Oloye J A Ajao, baba ẹka ẹgbẹ n a, Ologbe Dawodu a k ọ w e ẹka ẹgbẹ na l'Eko ati Alhaji Issa Williams t i nwọn lọ sin lọjọ na. Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ n a ni n w ọ n dide duro fun iṣeju meji gbako fun iranti awọn olo-gbe na lẹhin eyi nwọn se adura wipe ki Ọlọrun gbe wọn si afẹfẹ tere.

Alhaji Yakubu, ọ k a n ninu awọn ikọ ọmọ ẹgbẹ ti nwọn ti mba awọn kan ti nwọn da ẹgbẹ ọmọ Yoru ba silẹ, ti nwọn fi iwe pe wọn si ipade kan ni iwaju awọn ọ b a ilẹ Yoruba ni Ibadan, jiroro ni o kọ so-rọ:

Alhaji Yakubu la gbo-g o nkan ti nwọn ṣe ni ipade Ibadan na ye gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ ti o w a si ipade na ati bi awọn ti nwọn da ẹgbẹ ọmọ Yoru-sílẹ l'Eko ti sọ wipe ọpọ-lọpọ awọn en a n i nwọn fẹ wọ ẸGBẸ ỌDUDUWA ṣugbọn oruko yẹn ni nwọn ko fẹ.

O ni nkan ti nwọn nro ni wipe BABA-ISALE ni ẹgbẹ na jẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Afẹnifẹre (AG) o ni nwọn ni bi nwọn ba le yi oruko ẹgbẹ na pada, awọn ọmọ ẹgbẹ Y o r u b a tuntun ti nwọn sẹsẹ da silẹ ni awọn a ba wọn dapọ.

## Omo Olofin

O ni nigbati awọn fọrọ na titi, awọn ọba ti o wa nibẹ ba awọn da sii, o ni nwọn da a ni imọran wipe ki awọn yi oruko ẸGBẸ ọmọ ODUDUWA d a si Ẹgbẹ ỌMỌ Ọlọfin.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

Iwe Akoka Yoruba:

# Awon Oruko Ti A Nje Ni Ile Yoruba

(Lati Owo Alufa Atilade)

Oruko ti a pe ajá,
Ni aja njẹ,
Oruko ti a pe mala,
Ni ẹnia ngba,
A ki i pe ni ni abia,
Ki e ma sa gjogje
L'ọja ẹgua;
A ki i pe enia ni ọdẹ,
Ki o ma dẹ bi ọgẹdẹ
Oruko ti iya pe mi,
Nio mọ mi lara,
Oru ti baba sọ mi,
Nio afun mi l'okun,
Oruko ẹni ni ro ni,
Oruko ẹni ni ijanu ẹni.

Awọn Yoruba ki i ṣaba sọ ọmọ wọn ni oruko ti o ba wu wọn bikoṣepe ki nwọn wo ọmọ na tabi idile wọn ki nwọn to sọ ọ li oruko, nitori eyi ni a fi npa a ni owe wipe "Ile ni a nwo, ki a to sọ ọmọ l'oruko."

Gbogbo oruko ti a fi sọ enia ni o ni itumọ ni Ilẹ Yoruba. Bi a ba gbọ oruko ti a sọ ọmọ kan, a le sọ nkan dẹ yala nipa ọmọ na tabi awọn obi rẹ lati ara oruko na. Fun apẹrẹ, awọn ọmọ ti a bi ni idile ọlọla tabi oloye ni a ma fi oruko ti o bẹrẹ ni "Ade" "Ọla", tabi "Oye" bẹrẹ wọn bi Adesọla, Ademọla, Adekunle, Aderẹmi, Adeyẹmi; Oyewunmi, Oyetunde, Oyeronkẹ, Ọlawale, ati Ọlabisi. Ngbam ran Ọla, Ade, tabi Oye le wa ni ipari oruko bi Orioye, Ijaọla, Tẹ-nidade, ati bẹ, bẹ lọ.

Awọn oruko miran wa ti nwọn ntọka si iwa ti awọn obi ti ni nipa ọmọ na bi awọn abiku Apẹrẹ awọn oruko bawọnyi ni Kokumọ, Kosọkọ, Ikudayisi, Bamiduro, Fadimaiye ati Ikumapin, Nigbamiran, oruko yi le tọka si iriri awọn obi na ti ko kan Ọmọ na arara. Apẹrẹ iru awọn oruko bayi ni Babatunde, Iya-bọ, Adetokunbọ, Abidemi, Mosebolatan ati Ọlaniyọnu.

Awọn oruko miran wa ti o nfi ẹsin idile han. Iru awọn oruko bawọnyi ama bẹrẹ pẹlu oruko oriṣa ti awọn obi na nsin. Apẹrẹ iru awọn oruko bawọnyi ni

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Gesi Petu Si Ija Igboro Ilu Cyprus

Lati ọjọ meta wa ni ori-ṣiṣi ija igboro ti mbẹ silẹ larin awọn ara ilu Cyprus pẹlu Ijọba tobẹgẹ ti awọn alakoso ilu na fi ranṣẹ si wọn ni ilu Gẹsi wipe ki nwọn ko jọwọ ko awọn ṣọja jagunjagun wa lati wa ran awọn lọwọ. Awọn ṣọja meji kan niyi ninu aworan ninu mọto-ogun ti nwọn fi nsọ adugbo kan ni arin ilu na. Ara awọn ṣọja na ti Ijọba Gẹsi ko ranṣẹ si wọn niyi Wo oju ewe kẹfa fun aworan Olotu ilu Cyprus pẹlu Akọwe Ijọba Gẹsi kan.



# ELETI-OFE

(ANJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS
30, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
B. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIV. NO 904 SATURDAY JAN 18, - JAN 24 1964.


ORO OLOTU:

# Se Iya Nje Omo Yoruba...?

Iwe oro-ko-jokan ti a ri gba lati owo okan ninu awon okawe wa ti o ni oruko omo ABATI mu wa lokan pupo fun orisirisi oro ni 'na ni ekunrere nitori ti o so ti a fi fe fun yin ni anfani lati ka iwe Ogbe-a ko mo nkan ti a fi nse enia. E jowo enyin okawe wa, iwe oro-ko-jokan ti OMO ABATI ko si na niyi:

## Iya Ko Je Wa!

"Olotu, e jowo mo fi iteriba be yin, e gba mi laye ninu iwe irohin yin Eleti-Ofe lati jiroro lori oro kan ti a ngbo lojojumo lati nkan bi osu mefa sehin lenu opolopo awon asiwaju wa nile Yoruba wipe 'IYA NJE OMO YORUBA ?

'Gbolohun oro na je iyanu fun mi pupo ti o fi mu mi lokan lati se iwadi lenu oguniogo awon enia, awon ti a le pe ni omo Yoruba; emi ko duro se iwadi mi na ni igboro Eko, nitoripe ojojumo ni inu awon ara Eko ndun. Abo ni mo to wa pada sodo awon Yoruba Eko:

'Baba agbalagba agbe kan ni abule Majolagbe ti o ti ba won fi igbakan se oro ilu ri ni mo bere lowo re wipe nje iya ko nje awa omo Yoruba bi gbogbo nkan ti nlo si larin awon asiwaju wa lode isisiyi.

## Awon Oselu Niya Nje

'Alagba na ni 'omo mi, iya ko je awa mekunni awon olowo ti nwon nfi oro awon talaka sere ni iya nje.' O ni nigbati on ji lowuro oni egbaa meta (sile kan ati abo) ni o ba on ji pelu awon omo on ati iyawo on, awon si je. awon si ni itelorun,

Baba alagba na ni bi awon oselu ilu wa ko ba ta wa lodo awon kan, nwon ko le ri owo na jeun oju si ti ilu nisisiyi, awon mekunni ko se ko ni ijanu mo, e'eyi ni o jeki nwon maa so wipe iya nje omo Yoruba kakiri.

"Iya kan ko je wa rara awon baba oselu ti nwon fi gbese ko'e, ti nwon ko ri owo nan mo ni iya nje; awon ti nwon ri otito oro nile, ti awon ke so o ni iya nje.

## Eko Giga

"Nitoto, awon ilu-enia, awon awon anikanjepon, awon ti nwon nfi ise ijoba se ojusaju pelu awon ti nwon ko ro tomonikeji mo tara won ni iya nje.

# Iwe Si Olotu

'Olotu bi ogiri ba lanu alamu a ribi ko wo o: Emi na mo wipe awon iran kan (tabi awon enia ibile kan wa) ti nwon nje awon Yoruba ni obe-ehin. Nitoto awon Yoruba ko se fi owo ro sehin nipa eko-giga ati nkan gegebe sugbon ife ti ko si larin won ni o nfe so won di eni ehin larin awon Ibo ati Hausa lojo oni.

"Adura mi ni wipe ki Olorun ati alajobi le je ki a le fohun sokan nile Yoruba fun anfani ile wa ati awon omo wa.

Emi ni,

**Omo Abati'**

Oro ni e gbo lenu OMO ABATI enyin okawe wa, kinni enyin na ro nipa iya ti nwon nso wipe o nje enyin omo Yoruba yi?.


## MERCEDES — BENZ

*Vehicles are Built to last, to give many years, and many miles of trouble-free, economical Service.*

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Issa Williams D'ologbe

Awọn ọmọ ẹhin Jesu Kirisiti, awọn ti a npe ni Kiriyo ni Maleka kan ti kọ ọ sile ninu iwe-ẹsin awọn wipe IKU NI IGBẸHIN OHUN GBOGBO; BI ENIA LOWO YIO KU, BI ENI KO SI LOWO YIO KU; ẹsẹ bata mẹfa kanna ni ibusun olowo ati talaka ni iboji ti a gbe nlọ sin wọn si. Ko si nkankan ti o jẹki nsọ ọrọ bayi ju ti iku Ọgbẹni mi kan, Alhaji Issa Akangbe Williams ti o jẹ alaisi ni Olowogbowo ninu ọsẹ yi lọ.

## Lati Owo Ayiluka

Mo mọ Ologbe Issa Akangbe Williams nigbati owo niyi, nigbati pọnun kan wa ni pọnun kan ti ko ti da ṣile mẹfa ati kọbọ mejọ ti o wa nisiyi; nigbati awọn onişowo nṣe otitọ ti madaru ati Wayo ko ti da agbada ajiwọ fun wọn ti nwọn npa awọn Oyinbo rọ.

## Baba Onileke

Ọrọ ti mo nsọ yi ti ju ọdun marundinlogoji lọ, nigbana ni Ologbe Akangbe nta ilẹkẹ ninu şọbu kan ti o doju kọ ile Macaulay Ọlọbọ ni Palm Church Street ni ita Balogun l'Eko. Işẹ isowo (Commerce) işẹ ti o wu mi pupọ, mo si nkawe fun un lati ilu Oyinbo şugbọn awọn tişa mi ni mo ni lati ma rin mọ awọn ti o ba nşe işẹ onişowo yi larin ilu KI NLE RI ỌKAN, eleyi ni o mu mi de ọdọ Ologbe Akangbe.

Awọn ọmọ rẹ, awọn bi Muri Alade, Rashidat ati evi ti o di Adajọ-agba, Fatayi, ki a ma wulẹ sọ ti Wahab ti o di dokita nisisiyi, gbogbo wọn wa ni ọmọkekere ti nwọn nlọ si ile-iwe nigbana.

## Baba Oninure

Iru baba bi Ologbe Issa Williams şowọn ninu awọn Imale igbana. Ko fi ẹkọ awọn ọmọ rẹ şere rara, mo mọ eleyi nitoripe mo sunmọ pupọ, gbogbo nkan ti alagba fi nhan ọmọde ti o ba fara balẹ ni o si fi han mi; bi ko ba jẹun ana sun ki o sa ti ri owo ilewe fun awọn ọmọ rẹ yi ni o ma ndu nigbagbogbo.

O pa lasẹ wipe gbogbo iwe ti o ba dara fun awọn ọdọ ti mo ba ra lati ilu Oyinbo ni ki nma ra fun awọn ọmọ on ki nwọn le ni ẹkọ ile ati tode. Boya Rashidat ọmọ rẹ (aya Tokosi) ati Adajọ Fatayi ile niran awọn iwe pataki ti nwọn ki şe iwe ajọka ti ile ẹkọ ti ologbe baba wọn ra fun wọn nigba atijọ, emi Ayiluka mọ nipa awọn iwe na.

Ki a fi ọrọ ẹkọ silẹ nitoripe bi Ologbe Issa Williams ti nfẹ ki awọn ọmọ on lẹkọ ti o nfẹ ki awọn ọmọ ẹlomiran paapa jinna ninu ẹkọ, ki a wa tamọ ọrọ Ọlọrun. Olufọkansin ni mọ mọ ọ, ko fi irun kiki ni wakati marun şere rara nigbati mo mọ ọ.

Emi Ayiluka ti ọgbọn kọ nipa igbesiaye lọdọ Issa Williams pupọ idi rẹ leyi ti mo fi yaşọ leka ti mo fi lọ si ib isinku rẹ, ko nşe nitori irẹsi ti ao jẹ ati ọti ti ao mu pẹlu kọbọ kọbọ ti awọn ọmọ rẹ ati ẹbi rẹ yio ba mi.

Mo ki gbogbo ẹnyin ara Olowogbowo, ẹnyin Ijọ Imale Ahmadiya, ẹ ku a fẹku baba oninure. Anọbi ko gbee si afẹ́ẹ rere.

## Odun Awon Alarede

Lori gbogbo irohin awọn ẹjọ awọn alarede ti mo ngbọ wipe nwọn re si Kotu ni iwaju awọn adajọ wa mo ro wipe ODUN AWỌN AKỌKỌ ALAREDE ni ọdun yi ni lati jẹ ni Nigeria. Eeyi si mu mi niran nkan bi ọgbọn ọdun sẹhin ti gbogbo awọn iyawo alarede Eko nko ẹjọ nwọn fẹ kọkọ wọn lọ si ọdọ Ologbe Lọya A Kayọd. (baba Fani-Kayọde, nitoripe o mọ ọwọ ẹjọ awọn alarede şe pupọ ju.

Mo nran ọrọ imọran ti ọkan ninu awọn adajọ agba, Adajọ Webber, sọ fun wa ni Ita Tinubu nigbana, o ni nsọn ko şe eto igbeyawo alarede fun enia-dudu rara, nitorina ni ko jẹki emi Ayiluka gb'arede ara nitori nko le fi owo mi ran pasan fun obinrin ile mi wipe ki o ma a ti na mi lojojumọ.

## Ejo L'ale Ro ...

Mo gbọ wipe ọrẹ mi onifọto, Jackie Phillips ti o wa ni Ọpọpọ Ọdunlami l'Eko ti pe alarede iyawo rẹ lẹjọ ati lọya ti o yan alarede na lale, ti alarede na loyun fun. Mo tun gbọ wipe Ọusọji ọmọ tişa Odunjọ ti gbe iyawo alarede rẹ. Ọmọdeie lọ si iwaju adajọ Kotu wipe on fẹ kọ ọ silẹ nitoripe o le mu ọti amupara pupọju o si nşe tiyin pẹlu Iyẹn ni ko ye mi si.

## Bi Yoba Ko Nt

Ẹrin pa mi pupọ nigb ti mo gbọ wipe iyawo alarede ọrẹ mi kan gbe e lọ si Kotu nitoripe obinri kan bi ọmọ fun ọkọ rẹ l'Ebute-Mẹta, boya iyawo alarede yi ko mọ wipe ori ọmọ ni o npe ọmọ wa saiye; eleyi ni o jẹki ọkọ ke awọn ale ti iyawo alarede na fun un. Oju aiye ni ẹ ri yio! ọrọ awọn iyawo alarede kanpa.

(Wo iyoku loju ewe Kejọ)

BP PAYS ALL · BP PAYS ALL · BP PAYS ALL

Fun Ina dídá ati fun Imọlẹ

BP SUPERLITE
KEROSINE
L'ayo!




Ti o ba şepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri nà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titàn ati lati mã fi yinà Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

**E Ko Gbodo Taja Owo:**

# Ijoba Meka Fowo Kowori Ero

JẸDDA—Ko si ibiti ese ko si ile aiye, awọn alakoso ijọba ilu Mẹka paapa ti bu kuu ewo-ori ti gbogbo awọn ero ti o ba awọ ilu wọn yio ma san ki nwọn to wọ ilu.

Awa onirohin Eleti-Ọfẹ ti ngbọ finrinfinrin ọrọ efikun owo ori na ti pẹ sugbọn ako kọ ibi ara si a fi waya irohin kan ti a ri gba lọdọ aṣoju wa kan lati ilu awọn Larubawa ninu ọsẹ yi, eyi lo jẹ ki a tun se iwadi ọrọ na daradara lọdọ awọn alaṣẹ ilu wa ni Nigeria nibi.

## Owo Sise Ko Si

Ofin ti ọdun ni yio le diẹ fun awọn alejo ti nwọn ma a nṣe iṣẹ owo a nra a nta lọna Mẹka aitoripe Ijọba Mẹka ti ṣe ofin titun ti nwọn nfẹ gbe jade ti nwọn ba ti gba awẹ tan wipe alejo kalejo ko gbọdọ wa ṣowo ninu awọn.

Nwọn ni ẹsin ti nwọn wa sin ni awọn fẹ ki awọn alejo awọn tẹju mọ. Nkan ti o fa idi ofin yi ko ye wa si, ṣugbọn a gbọ wipe lati di awọn Alhaji eniwayo ti nwọn ma nwa ṣe iṣọ wayo ninu na lẹdọdun lowọ ni.

## Ile Ero

Irohin ti a tun gbọ nipa ọrọ Mẹka ni ti ile egbogi ti Ijọba Nigeria fẹ kọ sibẹ fun anfani awọn ogunlọgọ obinrin ati ọkunrin ti nwọn ma nṣe amodi lọdọdun, ti nwọn ko rẹni tọju awọn ti nwọn ma nku sibẹ.

A gbọ wipe Ijọba Apapọ ile Nigeria ti ṣe wahala titi lati wa ilẹ ola ti nwọn le fi kọ ile-gbigbe si ni Mẹka fun awọn Imale ti o nlọ sibẹ lọdọdun ṣugbọn awọn ko ri ilẹ.

Ju gbogbo re lọ, a gbọ wipe Ijọba yio gbe iwe ikede jade laipẹ yi lori gbogbo ikilọ nkan ti awọn ara Mẹka ni awọn ko fẹ ninu awọn ni ọdun yi.

# Akoka Yoruba

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ogundele, Ogundare, Ṣangolana, Ṣangodoyin, Ọyawumi, Ọyarẹmi, Ọshungbemi, Ọsunrẹmi Efuntunde, Efunwale, Ọrokuale, Ọrogbemi, Egunjọbi ati Atọ. Orukọ eniti a npe ni Ato ni obinrin ti o le wọ igbo igbalẹ egungun eyiti awọn obinrin miran ko le wọ, bikoṣe kiki okunrin nikan. Ọmọ ti o we ibi mọ ara tabi ọwọ bi paṣan egungun ni a npe ni Ato tabi Amuṣan t'o ba jẹ ọkunrin.

Awọn orukọ miran wa ti nfi iriri han n pa ti ọmọ na papa bi, orukọ awọn abiku. Diẹ ninu awọn orukọ bayi ni Fidimaiye, Kokumọ, Kukoyi, Kosọkọ, Ikumapai. Awọn orukọ miran nso iru ibatan ti o wa larin iya ati baba nigbati a fi bi ọmọ na. A le toka si awọn orukọ wọnyi fun apẹrẹ ohun ti a wi yi: Ọrẹdọla, Ọrẹdapọ, Ibidapọ, Bandele, Abiọna, Abisoye. Awọn orukọ miran ntọka si akoko ti a bi ọmọ na. Apẹẹrẹ ira awọn orukọ be ni wọnyi: Abiọsẹ, Abiọdun, Abejide, Ojọawe.

Awọn orukọ miran nje orukọ amutọrunwa. Awọn elewọnyi ni orukọ ti a ma fi npe gbogbo iru ọmọ ti ta bi ni ipo kanna. Fun apẹrẹ ọmọ ti a ba kọ bi larin awọn ibeji ni a npe ni Taiwo, eyiti a bi kẹhin ni a npe ni Kẹhinde. Ọmọ ti a ba bi tẹle awọn ibeji ni a npe ni Idowu, eyiti a bi tẹle Idowu ni a npe ni, Idogbe ti o ba jẹ ọkunrin, bi o ba si jẹ obinrin, a npe ni Alaba. Awọn ọmọ ti a ba bi ni ibẹta ni a npe ni Oke, Ọkọkan iru awọn ọmọ be ni a npe ni Ẹta Oko. Ọmọ ti a ba bi ti o jẹ ẹlẹkanra ti ako wẹwẹwọ ni ọjọ ti a bi i, ti ẹkun na pọ rekọja ni a npe ni Oni tabi Asa, Eyiti a bi le Oni ni a npe ni Ọla, eyiti a bi le Ọla ni a npe ni Ọtunla.

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)



# Ore Meji Pade Ara won

**Rogbodiyan ilu Cyprus ti a gbo wipe nwon npa ara won le lori, ti nwon nranse si ilu Gesi wipe ki nwon fi awon soja jagujagun ranse si awon si ni o mu akowe awon ilu ajumose pelu Gesi, Olola Duncan Sandys ti o wa lapa osi aworanyi foju kan Archibishop Makarios ti o wa ni apa otun aworan yi. Nwon nse asaro bi rogbodiyan ilu na yio se pari.**

# Attack On Human Want Is Major Goal Of Johnson Programme

**WASHINGTON, — President Johnson's domestic programme-like much of his international programme—strongly reflects the ideal of eradicating poverty wherever it may exist.**

This includes "pockets of poverty" in the United States, which in past years has moved to new heights of economic strenght and prosperity and yet - for reasons of the mere passage of time and rapid technological progress-has long struggled with a paradox. It is that some geographical regions and human groups have not shared in the rising affluence.

This, to Mr. Johnson, is patently illogical, wasteful and unworthy of that kind of a progressive administration he plans to lead.

It is therefore a cornerstone of his program to attack "pocket of poverty" in the United States no less than in the world.

That, in fact, is what he has added to the Kennedy proposals before Congress and addition which puts the Johnson Program in a straight line of succession to the new deal, the fair deal and the new frontier of his democratic predecessors in office.

But rather than simply attaching a name to it, Mr. Johnson proposes specifics and details.

Since it carries beyond the social philosophy of Roosevelt, Truman and Kennedy, it is impossible to imagine that the Jonson plan would not become one of the most heatedly debated issues in election campaign this fall. The issue of government involvements in human affairs has long been a a main bone of contention between the major groups in both parties.

But President Jhonson's motivation is neither simple politics nor strictly materialistic economics. Perhaps his most fervent and impressive plea was for passage of the civil rights bill.






# Disarmament Examined In New Booklet

**LONDON-The progress made in disarmament negotiations so far, and the chances of reaching agreement on this vital issue, are analysed in a booklet prepared by the British Foreign Office and published in London this week.**

Entitled "The Key to Disarmament", the booklet is being made available throughout the world.

Noting that the partial nuclear test ban treaty has given rise to hopes that old difficulties may now be overcome in an atmosphere of better mutual understanding, the publication examines the prospects for disarmament.

Disarmament it says, is not only the most complex of all international problems; progress on it must depend on parallel advance in solving outstanding political problems, and the key to agreement is the building up of confidence between nations.

Current Western and Russian disarmament plans are summarised, and there is a detailed chronology of main developments in the fields of disarmament and banning nuclear tests.

The destructive power of nuclear weapons is so great that both sides have almost certainly, ruled out major wars as an instrument of policy.

It stresses that the only real safeguard against "cheating" in which a power could gain significant military superiority by secretly rearming, is international inspection or verification to make sure that any disarmament agreement is carred out by all.

## New Secretary—General Of Council Of Europe

LONDON — Mr. Peter Smithers, M.P., Parliamentary Under Secretary of State for Foreign Affairs, was yesterday, Wednesday, elected Secretaty General of of the 17 nation Council of Europe.

Mr. Smithers, who is 50, succeeds Signor Lodovico Benvenuti of Italy who retired last year. He is the first Briten ever to be appointed to th post and in the second ballot he won 75 votes - then above the required majority.

# Egbe Omo Oduduwa Ni Awon Ko Pa Oruko Da

(O bere lati oju keta)

Alhaji Yakubu ni Dokita Akanni (Daddy) Doherty ti o je okan ninu awon asiwaju iko ti nwon lo si ibi ipade na so pato oro fun won ni Ibadan, o ni awon ti awon wa si ipade na ko lenu oro naso ju wipe ki awon lo jise fun gbogbo omo egbe lo, iru oruko ti awon ba fe. O ni nitori eyi ni awon se pe ipade yi lati gbo tenu awon omo egbe ki awon le mo ise je.

## Iya Ko Je Yoruba?

Enikan ti o tua soro ni apejo ipade na ni on se akiyesi wipe awon enia kan nse ikede kiri wipe IYA BURUKU NJE AWON OMO YORUBA NISISIYI, GBOGBO AWON OMO EGBE ODUDUWA ti o wa nibe ni IYA KAN KO JE AWON RARA. AWON ti nwon nta omo Yoruba nitori owo, awon ti nwon ra moto ti nwon ko r'owo repo ni iya nje. Nwon ni opolopo won ni awon mo sugbon awon ko ni daruko won.

Obinrin kan wa dide ninu awon omo egbe na, oruko re nje Iya afin (Mrs) Viatonu (enití gbogbo enia mo adape oruko re si SISI OFFA) on 'na tun se okan-ko-jokan oro nipa awon omo Yoruba ti nwon ni ko si irepo larin wa. O ni gbogbo awon obinrin ni awon mo ise ribiribi ti awon omo Egbe Oduduwa tise lati odun medogun ti nwon ti da egbe na sile.

Iya afin Viatonu ni bi awon baba egbe omo olosu'meta yi ba mo nkankan ti o buru ninu nkan ti awon egbe 'omo Oduduwa nse ko dara, ki awon na wa, aye wa fun won lati di asiwaju egbe na, ki nwon si wa ba wa tun gbogbo nkan na se leto-leto.

Okan ninu awon o m e Egbe Oduduwa Obinrin ti nwon wa si ipade na tun soro pelu Ogbeni "Ewokosi Longusi, o ni ko tile ye awon ara E k o ki nwon ma bu enu ate lu ise ribiribi ti awon o m o Egbe Oduduwa se fun Yoruba Ogbeni Ewokosi ni awon ara Eko ni awon omo Egbe O uduwa ko s i n nigbati nwon da egbe won na sile o ni bi enikeni ko ba mo eyi, o ni awon ara Isale-Eko mo.

Lehin e y i ni O m o b a Osipede okan; ninu awon iko ti o w a lati Mushin, ba dide o si da ni imoran wipe awon fe mo bi gbogbo awon ti o wa si ipade na ba faramo abá wipe ki a w o n yi oru o E G B E OMO ODUDUWA pada si EGBE OMO OLOFIN, gbogbo won n i a w o n k o fe yi oruko pada.

Die ti a ye wa l ti daruko niyi ninu awon o m o egbe ti o wa si ipade na ni: Alhaji A. K B e l l o, Ogbeni J. A. O d e k u, Alhaji Masha, O m o b a "Erukobodo" Adefasin, Ogbeni Abiola ati Fadipe, akowe awon omo egbe na pelu S. A. Oshodi.

# Ayiluka Fe Di Akapo-owo Awon Egbe Omo Olofin

(O bere lati oju ewe Karun)

## Morgan Adajo Ibadan

Mo be ore mi, Adeyinka Morgan ti nwon sese fi je olori fun gbogbo awon adajo agba ti nwon wa ni Ipinle Iwo-Orun yo. A ko mo ibiti ori gbe MBA ESE RE· Ake mo wipe Lojo ti gbogbo wa jo nsere omode po ninu Ogba Sosi Iporo-Ake, ti baba wa, Alufa N O A Morgan ma nse iwasu fun wa wipe ki a foju seko wa, ko si eniti o mo wipe Adeyinka yio di oga a w o n adajo-agba loni.

Ninu wa ni awon bi Robinson, Taiwo Martins, Tugbe'e Morgan, Ibikun'e John, Olalekan Onatade, Coker ati Lad po Sosan wa. Bi a ba kuro ni Iporo a nlo si odo awon Showande ati Berckley l'Ake. Awon omo Morgan ko gbodo bawa sere ni oja Ibarapa ale nitotipe Alufa Morgan a ba won wi. Lekansi, mo be ore mi Oga awon adajo na yo.

## Omo Olofin

Nwon ni bi a ko ba tori epo je isu, a le tori isu je epo: nigbati mo ri ore mi Fagbenro omo Beyioku ninu awujo awon Omo EGBE OLOFIN ni Satide ti o koja, o wu mi ki emi na je okan ninu won nitori ti ore mi Fagbenro nitoripe omo Olofin Iseri nii, o si je oye pataki nibe, emi ti mo eleyi ti pe. Ti nwon ko ba ni pa itan fun mi, emi na fe d'omo egbe Olofin mo si fe JOYE AKAPO OWO nibe ki ale ma mo bi eto ti nlo si nitoripe ngo fe ki nwon gbe nkan koja lehin mi rara. Oro re o enyin omo Egbe Olofin.

## Ija Awolowo pelu Akintola Fe Pari

(O bere lati oju ewe Kinni)

Awon kan ni eto bi gbogbo nkan yio tise lo daradara, ti gbogbo awon omo Yoruba yio se fi imo sokan lati gbaruku ti EGBE OMO OLOFIN ti nwon sese da sile ni nwon jo so. Nwon ni Oba Ile Ife ni oruko Oduduwa na lo nje Olofin ko si iyato nibe rara, se bi enia ba loruko o ni lati ni oriki.

A tun gbo irohin wipe Dokita Akanni Doherty ("Daddy") ko sun, ko wo nse ni o npara Ibadan ati Abeokuta nigbagbogbo lori bi ija na yio ti pari. Ni ibere ose yi ni a gbo wipe Dokita na lo si Ago-Owu ni Abeokuta lati lo ba Alhaji Adegbenro soro bi ija na yio tise pari.

Gbogbo aso ko ni a nsa lorun, sugbon a gbo wipe awon ti yan awon iko kan ti yio jiroro lori oro ija Oloye Awolowo ati Akintola.



Oloye OBAFEMI AWOLOWO

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor; (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467.